# AARUN HIV LARA AWON OMODE.

Ajakale arun HIV si n gbile si. Kokoro HIV ni o maa n fa arun yi, eyi si ti n po si ni arin awon omode. Pupo ninu awon to ni arun yi , ti iku si n pa nitori arun yi , ni a ri ni awon orile ede ti won si n dagba soke.

Opo ninu awon omo to ni arun yi li o ko arun yi ni igba ti won wa ninu oyun, tabi ni akoko ikunle, tabi lati inu omi oyan iya won. Iwadi si n lo lati mo boya arun yi a maa gba inu olobi koja si ara omo ninu oyun, sugbon awon onimo ijinle ni ero wipe ni igba ti eje iya ati omo ba da po ni arun yi le koja lati ara iya si omo. Ti abiyamo ba lo akoko pupo ninu irobi ki o to bi omo le ran kokoro yi lowo lati ri aye wo ara omo. Awon omode ati agba tun le ko kokoro HIV nipa gbigba eje ti o ni kokoro yi ninu, tabi nipa fifi ipa ba eniyan lopo ni igba ti iru afipa banilo yi ti ni kokoro yi lara

Iwadi ti fi han wipe, fifun omo li oyan le ran kokoro arun yi lowo lati koja si ara omo bee, a si ni lati ri wipe awon abiyamo ni oye yi. Ni igba ti o ba se se, a le gba awon ona miran lati wa onje miran fun iru awon omo bee.

Ipa meji ni arun HIV le ko ni ra awon omode. Ida kan ninu marun awon omo ti o ni arun yi a maa jiya pupo li owo awon arun miran to li agbara gidi li kete ti a ba ti bi won, ti opo ninu won si maa ku ki won to pe odun merin. Ida merin ninu marun awon omo bee li arun yi a maa je ni iya diedie. Opo awon omo wonyi ko ni le dagba soke bi o ti ye. Gege bi awon agba ti o ni arun yi, opo awon aisan pepepe li o maa n yo awon omo bee lenu. Otutu aya si je koko ninu arun eyi ti o maa n se iku pa awon omo bee.

O soro lati se ayewo  fun kokoro HIV lara awon ikoko, papa ju lo ni kete ti a ba ti bi awon omo ikoko. Opo awon ikoko kii ni ami kankan ti o le fi arun yi han rara. O le to osu mejidinlogun leyin ti a ti bi omo ki a to le se ayewo ti o daju fun awon omo bee. Idi ni wipe awon eroja olopa ara ti o ti koja lati ara iya si omo ni inu oyun, a maa pee ki won to tan patapata lara awon omo tuntun.

O se Pataki lati se ayewo to peye fun gbogbo awon omo tuntun ti o ba se alababapade kokoro HIV yala ninu oyun tabi li asiko irobi. Awon ayewo wa lati se ni kete ti a ba ti bi omo tan, a tun ni lati ye awon omo bee wo leyin ose merin si meje, ati leyin ose merindinlogun ti a ti bi omo tan. E yi se koko lati tete fi han boya iru omo bee ti ko kokoro HIV. Ti a ba si ri wipe kokoro yi ti de ara omo bee, awon ayewo to li agbara wa eyi ti o le fi han dajudaju wipe kokoro HIV wa li ara iru omo bee. Pelu awon ayewo alagbara wonyi, o se se ki a mo wipe kokoro yi ti de ara omo leyin osu meji si meta ti a ti bi iru omo bee.

A ni lati gbiyanju lati ri wipe a se ayewo fun awon abiyamo, ki a le mo boya arun HIV wa li ara won, yala ni akoko ti won wa ninu oyun, tabi ki won to li oyun. E yi se Pataki ki a le dena kiko arun yin ran awon omo won. Awon oogun oyibo ti wa eyi ti a le lo fun awon aboyun lati dena kiko arun yi ran omo ti o wa ninu oyun. Ogun yi je iyebiye, eyi ti opo eniyan ko si le ra lati lo. Iwadi ijinle si ti fi han wipe , awon oogun kan ti wa eyi ti owo won ko po pupo, ti o si le wulo pupo lati dena kiko arun HIV ran omo ti o wa ninu oyun. Iru oogun bayi si ni iwulo gidi ni awon orile ede ti opo awon eniyan ibe je mekunnu. Ni afikun, sise ise abe lati bi omo a maa din kiko arun yi ran omo ku lopo, agaga ti a ba se eyi pelu lilo awon oogun ti a ti so oro won yi.

O to isori merin ninu awon oogun oyibo ti o wulo gidi lati se itoju awon omo ti o li arun HIV. Isori kookan ni ise pato lati se ki a le gbogun ti awon kokoro buburu yi.

Translated into Yoruba Language by:
Dr. ADEOTI, Abolaji.
Pretoria, South Africa.
22 / NOV/ 2007.